# IROHIN IMOLẸ

IMOLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA
No. 732 TUESDAY, JUNE 30 1964 (2D)


## Ewe Sunko! Pidanpidan Kan Pa Ara Rẹ!!

ILỌRIN:- Ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi ni omidan kan ti oruko rẹ njẹ Momoh ara Fulani ti o ngbe Ibugbe Gambari ni Ilorin gun ara rẹ nigbati o npidan " Okigbẹ ida pẹlu omi".

Pataki idan ti Momọh npa ni idan okigbẹ ti ki i jẹ ki ọbẹ o ran ni. Bi o ti de lati pidan ni gbogbo enia ti pejọ sibẹ nwọn si nyombo rẹ nigbati o bẹrẹ rẹsi e pigede tabi ọfọ eyi ti i o ma a-nse ki o to ma pa idan, gbogbo wọn si npa atẹwọ ti nwọn nhu ku u! ti nwọn npariwo ge e!!

O si jo yika agbo fun idaraya ibẹrẹ idan o si tun gba ọpọlọpọ ipẹsi lẹhin na ni o wa fada ada kan yọ ninu akọ rẹ oju ni o kọkọ fi nyọ lẹhin iyẹn ni o tun bẹrẹ si fi idi yun ikun tabi (agbẹdu) rẹ ṣugbọn lori eleyi ni ewe wa sunko si nsi ni ida na wo agbẹdu rẹ lọ ki o to fura si i pe okigbẹ on ti bajẹ oti ṣubu silẹ agbara ẹjẹ si ntu jade lati inu agbẹdu rẹ bi omi ẹrọ.

Lẹsẹkẹsẹ oran di pẹ ntuka bo o lo o ya ngmi gbogbo awọn oluworan ti parẹ loogan Olori abule Momoh yara wa tete fi oran na han awọn ọlọpa Ibile nwọn si ti gbe ẹ lọ si Ile-wosan lakulaku.

Bayi ni pidanpidan Abule Gambari Ilọrin fi ara rẹ pidan E sọ dọwọ yin o ẹnyin alabamọ da,

## Okeiṣoro Ati Bukata Awọn Oṣiṣẹ Yio B'opin!

# IJỌBA FẸ DIN'WO ILE KU FUN GBOGBO ENIA LEKO

## Pọnun Meji (£2) Fun Yara Kan L'osu!

EKO:— Gbogbo enia lo bẹrẹsi yọ ṣẹṣẹ kakiri gbogbo ile iṣẹ Ijọba ati ti awọn Oyinbo oniṣẹ Ajẹ nigbati irohin de si etigbọ gbogbo awọn oṣiṣẹ na ni kutukutu owurọ ana ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu yi, pe, Ijọba yio paṣẹ pe gbogbo awọn onile ni Eko (ati Ebute Mẹtta, Yaba ati Surulẹre ko gbọdọ gba ju pọnun meji £2) lọ loṣu fun yara kan.

Adehun ati eto yi ni awọn Aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ati awọn Aṣoju Apapọ Ijọba Na ijiri kọwọ bọ iwe adehun rẹ ni Eko lana ninu Ile Igbimọ awọn Agba oṣelu.

Agbọrọsọ Ijọba ṣe alaye fun oni 'e Irohin wa Ejon'gboro pe, Ijọba yio yan Igbimọ kan sode laipẹyi, ti yio ṣe iwadi iye ti awọn oṣiṣẹ ngba ni oṣu kan ati iye ti awọn oṣiṣẹ nsan ni owo ile, ati iye ti awọn oṣiṣẹ nsan ni owo ile, ati iye ti o nṣẹku nilẹ fun oṣiṣẹ kan lẹhin ti oṣiṣẹ na ba san owo Ile tan ninu rẹ.

Bakanna ni Igbimọ na yio tun wadi nipa iye owo ti oṣiṣẹ kan fi njẹun ni oṣu kan, nipa ṣiṣe bayi, Ijọba yio mọ iye ti nwọn o palaṣẹ lati ma a ta ọja.

Ijọba yio yan Igbimọ oluwadi na lati maa lọ lati ile de ile ti nwọn yio si mọ iye ti awọn oṣiṣẹ nsan fun yara kan ati bi yara na ti dara to ati ẹhinkule i e na, ati iye t o si yẹ ki iru ile na o to tabi iye ti o yẹ fun awọn olugbe inu ile kan.


Alhaji H P. Adebọla


Oloye Okotie-Eboh

Ṣugbọn nigbati Ijọba ba yan Igbimọ Oluwadi na, Ijọba yio pe awọn enia diẹ ninu awọn onile Eko, diẹ ninu awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ ati awọn Asiwaju Apapọ Ijọba ninu Igbimọ oluwadi pẹlu awọn Aṣiro owo ati Iye ọja.

Igbimọ na yio tun ṣe iwadi nipa iye owo ori ti oṣiṣẹ kan nsan ati iye owo - ile ti oṣiṣẹ na nsan. Nwọn o si wo ẹgbẹ mejeji wo bi o ti ri, ki nwọn o si mọ ibiti ẹru na pọ si.

Bakanna ẹwẹ, ni awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ tọ pe awọn ọja tin an ju lọja ati ninu awọn ile Itaja.

Igbimọ awọn Asiwaju ẹgbẹ osiṣẹ ṣe alaye pe, bi ile kan ti wulẹ ki o dara to ni Eko Yaba Ebute-Mẹtta Surulere Apapa ile na ko gbọdọ hanju pọun meji losu fun yara kan lọ

Bakanna ẹwẹ awọn Asi-waju ẹgbẹ oṣiṣẹ na tun sọpe ile ko gbọdọ han ju pọnun kan sile mẹwa (£1: 10/) lọ ni Ibadan Kaduna Enugun tabi Ibinni

Gbogbo awọn nkan wọn yi ni Apapọ Ijọba gba fun awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣisẹ lana nwọn si tun ṣe ileri pe kiakia ni awọn yio tete ṣe eto na laipẹ

Ṣugbọn Ijọba ṣe ileri pe, gbogbo rẹ ni Igbimọ oluwadi na yio wadi, lẹhin iwadi na, Ijọba yio wa paṣẹ iye ti o yẹ, ti o si to lati ama ta ọja.

Igbimọ oluwadi na yio se gbogbo eto wọn yi, lẹhin iwadi yio wa fi abọ fun Apapọ Ijọba


Ọgbẹni Imoudu

Apapọ Ijọba ti gba wipe, gbogbo eto na ni awọn yio se, ki alafia ifaiyabalẹ ati idẹra o le wa fun awọn osisẹ, pa apajulọ, inu awọn osisẹ ti onile wọn ti di ẹru wiwo le lori ti wọn si sọ wọn di "onisowo" ti wọn ngba owo ile iye ti o ba ti wu wọn lọwọ wọn.

Apapọ Ijọba sọ pe ti oluwadi na ba pari iṣẹ rẹ tan, Ijọba yio paṣẹ pe, ẹnikẹni ko gbọdọ fi yara kan haya ju iye ti Igbimọ na ba wi lọ.

Bi enia kan ba si lọ fi agidi, orikunkun ta bi ṣeeṣi ru ofin na, Ijọba yio mu oluwarẹ gẹgẹbi arufin, awọn o si fi iya ti o ba tọ jẹ oluwarẹ,

Awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ti fi ọwọ si Iwe adedun na l'Eko lana bẹni awọn aṣoju Apapọ Ijọba na tun fi ọwọ si iwe na pẹlu.

Bi adekun na ba ti nlọ, ẹ o ma a gbọ o.

## Dokita Allen Mu Ori Bọ!

EKO:- Ile ẹjọ gigajulọ fun ilu Eko lo kun fun awọn enia ti o wa gbọ bi ẹjọ ti Ọgbọni Oyinbo kan ti o njẹ Victor Leonard Allen, pe lori kikuro ti o fẹ kuro labẹ aabo Ọlọpa" niwaju adajọ Ọlọla Charles Daddy Onyeoma ni ilu Eko

Nigbati awọn pe ẹjọ ti ẹ ba ṣe na nile ẹjọ na lana ni adajọ Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya sọ fun adajọ agba na pe, lori ibura ti awọn ti se ni awọn duro le lori on si mọ wipe Ọgbẹni V. L. Allen ko ni kọ ja ofin nitorina ki jẹ ki o kuro ni aabo Ọlọpa.

Ni agbẹjọro fun Ijọba Ọgbẹni C. H. E Miller sọ wipe, on ko lodi si ọrọ ti agbẹjọro

WO OJU EWE KẸFA

# IWE SI OLOTU

## Omu-Aran Nfẹ Iranlọwọ Ijọba

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi laye ati kesi Alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Omu Aran ati papa julọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa Naijiria lati bojuto awọn ọna to wọ ilu na ati pe ọpọlọpọ awọn ọna na ni ko dara fun awọn awa mọto ilu Omu Aran si kuro ni ilu ti ko gbọdọ ma ni itọju rara ni Ipinlẹ yi.

Inu wa yio dun pupọ bi awọn Ijọba na ba le ṣe ayewo awọn nkan wọnyi.

Eyi to si tun njẹ nkan pataki ni ina elẹntiriki pẹlu omi ti ko si ni igboro inu ilu wa yio dun bi awọn alaṣẹ Ijọba ilu na ba le tete ṣe awọn nkan wọnyi fun wa.

Ẹku iṣẹ o.

Emi ni
Joseph Ọlatunji
OMU—ARAN

## A Nfẹ Itan Ekun Oro

Yio jẹ didun inu mi ti Olotu iwe Irohin ba le ba mi tẹ ọrọ mi yi jade ninu iwe nyin to njade lojojumọ ki awọn agbagba to wa ni ekun mẹsan Orole foriko ki nwọn pa imọ pọ lati rẹ itan ilu kọọkan sinu iwe Irohin Imọlẹ fun wa lati ka.

Awọn ọmọ ilu wa mọ itan awọn ilu miran nwọn mọ itan ilu ajeji o wa jẹ nkan ti o buru ju pe nwọn ko mọ itan ilu wọn nitori idi eyi ni mo ṣe fẹ ki nwọn tẹ awọn itan na jade fuu gbogbo wa lati mọ.

Ekun Oro ko kere larin ilu to wa ni Ipinlẹ Ariwa a mọ itan wọn, ki t'ọmọde tagba le ma yangan itan ilu wọn.

Nitorina abẹ ẹnyin baba wa ọrọ na di ọwọ nyin o agbalagba ki wa lọja ki ori ọmọ tuntun wọ foto ọṣẹ bi owe o.

Mo dupẹ pupọ fun aye ti ẹ gba mi ọkọ Oba ko ni ṣa nyin lesẹ Olotu

Emi ni
M. A. O. Oyedun
ORO

## Okiti-pupa Nfẹ Ina Ilẹntiriki

Olotu, jọwọ gba mi ni aye lati kesi Ijọba rere ti ipinlẹ Iwọ-orun lati fun ilu wa ni Ina-Ilẹntiriki

Aiko si ina Ilentiriki ni ilu wa yio jẹ wa ni iya pupọ, nitorina abẹ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun lati fun wa ni ina na ni kiakia ki awa na le jẹ anfani ninu eto idagbasoke ọdun mẹfa ti Ijọba Apapọ i ṣe kalẹ.

Ina ti a o ni yi o ma mu ilu wa wa ni okunkun ni, bẹsini ilu wa ko kere ninu awọn ilu ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ-Orun, Inu wa yio dun pupọ bi ẹ ba tete ba wa fa ina si ilu Okitipupa.

A o ma reti yin o.

Emi ni
John O. Medi,
OKITIPUPA.

## Nibo Ni Orlando Babs Lọ

Olotu jọwọ fun mi ni aye kekere kan ninu iwe Irohin-Imọlẹ rẹ aladun lati fi bere Ọgbẹni ti o pe orarẹ ni Orlando Babs, ti o ma fun wa ni irohin ere Ije Bọọlu ati ti ẹsẹ jija rẹ ninu iwe yi,

A ma ngbadun ọkunrin yi gan ni, nitori bi ere bọọlu ati ti ẹsẹ ti nlọ si kakiri agbaiye paapa ni asiko ti Ere Tiger ati Gene Fullmer ni o fun wa ni irohin na ni ojojumọ ṣugbọn ojẹ iyalẹnu wa lati bi oṣu mẹwa ako gburo rẹ mọ, awa fẹ bere lọwọ olotu boya oti kuro ni abẹ yin tabi olọ si irin ajo.

Olotu, ẹjọwọ bi oba jẹ pe oṣi wa ni abẹ yin a nfẹ Orlando Babs ki otun ma fun wa ni Irohin ere ije, gbogbo orungbẹ rẹ si nda wa pẹlu alero pe olotu yio tete bawa ṣe eto yi ni kiakia.

Emi ni,
Armostrong ADE,
Kumasi-Ghana

## Njẹ E Fẹ Obinrin Bi?

Olotu, Inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye lati bere lọwọ awọn Alaṣẹ ẹgbẹ Imọlẹ Alye boya ẹgbẹ na wa fun Obinrin tabi Ọkunrin nikan ni ẹ fẹ ninu ẹgbẹ na.

Nitori ohun ti o mu mi bere nipe lati ọjọ ti ẹ fi nṣe ipade a ki gbọ pe ẹda Oruko Obinrin pe o wa si ipade, nitori idi eyi ni o mu mi bere boya ti Ọkunrin nikan ni.

Mo fẹ ki Alaga ẹgbẹ na ṣe alaye fun mi nipa ibere nwọn ti o ba jẹ pe bi Ọkunrin ati obinrin a wu mi ki gbogbo awọn obinrin ẹlẹgbẹ mi jọwọ ki nwọn jẹ ki a wọ ẹgbẹ na fun ogo ilẹ wa nitori ko si nkankan ti Ọkunrin le ṣe ti Obinrin ko le ṣe.

Emi ni,
Ọlawunmi Ọrẹlaja
EKO

REMAIN YOUNG
100 YEARS
Details:-Add,
C. T. Hospit l, (R. Y)
Azad Market. Delhi
6. India

## EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fihan gbangba ibiti Jẹdijẹdi rẹ gba wa lara rẹ s nyọ o lẹnu nigbagbogbo.Ibẹ na npe ni "omusu tabi ibo idi enia ib a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amedi ti o buru iti pataki fun Ọkunrin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapani

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisiyi ti nwọn ma a pọ lowo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mewa ninu awọn ogu ni ole ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe beyabi wọn ba lọ si ile lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa o ro bẹ rara Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun ẹrẹ bakana Orişirişi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mọ igbọ ṣẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pup jumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ p Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọ pupoju nigbakugba ọdi ori şirişi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omuṣu tabi i jo ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnsẹ tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbọn tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuṣu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbog "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣẹṣẹ wa idi rẹ kio si danwo orişi i mẹ a daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia yio de si ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata nigboro Naijiria yakejado bere ni:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES

8, Palmchurch Street, Lagos
ATI NI AWON ŞOBU IBADAN:—
IŞẸ OLODUNMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe Igbeyawo
KỌWE SI ILE—IṢẸ—ERỌ ITẸWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgbose Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
KETEKETE NI ERO ITEWE WA NHAN
OWO POKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ko si ri iyato

# Ọlọrun Gba Wa Lọwọ Opurọ Kẹ Ni Ma Ni

**Awọn enia Orisi meji ni o mbẹ ni aiye awọn enia orisi meji ni o wa ni orilẹ Yoruba ilẹ ti Edumare fi ta wa lọrẹ lati ma a lo si.**

Lati ma a ba ara wa lo ni ọna ẹtọ ati ẹye. Şugbọn o se ni, ni a anu lati rii pe, awọn kan wa ti o jẹ pe, iṣẹ ibi, iṣẹ eşu ni nwọn ni ifẹ gidi si, ti nwọn si fi nṣe ayọ oşi.

Ayọ lẹda ni wọn. Nwọn si fẹran okunkun Loru ni nwọn ma a npete-pero ni nwọn ma a nṣiṣẹ ibi ni nwọn si ma a nba enia jẹ.

Irufẹ awọn enia bayi ni awọn orişi kini Irufẹ awọn enia bayi ni nwọn ma a nhu iwa kẹ ni ma ni.

Ti nwọn ba ri ọkan ninu ẹbi wọn tabi ninu aburo wọn ti Ọlọrun gba adura rẹ, inu wọn yio baje.

Nwọn yio si ma a sa gbogbo agbara, nwọn yio si ma a pete-pero lati wa ibẹru fun eni na ti Ọlọrun gba adura rẹ. Nwọn yio si fun un ni orişrişi orukọ lati ba a jẹ. Nwọn ko ni şe iranti alajọbi nwọn ko ni şe iranti Edumare.

Nwọn ko ni ibẹru Ọlọrun lọkan Alakowaba ni wọn. Ẹoi ibi ni wọn kẹnimani nwọn kiyesi i igbesi-aiye irufẹ awọn enia bayi ki i dara rara; Nwọn a ma bosi adugbo ba enia jẹ. Nwọn ko si ni ifaiyabalẹ ni igbehin aiye wọn Ọlọrun ti ki i gbe ẹbi fun alare yio si san wọn ni ẹsan ibi işẹ wọn lẹkunrẹrẹ Nwọn ki i sọ ero ti o dara.

Awọn enia orişirişi keji şọwọn ju fadaka ati wura lọ, Ni gbogbo igba ni nwọn nẹ lati şe iranwọ ire fun ọmọ enia ẹgbẹ wọn, ni igba gbogbo ni nwọn nfẹ lati bo ọmọ enia lasiri. Nwọn ki i şe onisọkusọ bi ẹja, Bi nwọn ba ri ẹbi wọn tabi ọrẹ wọn ti nkan n dara fun, inu wọn yio si ma a dun si i.

Nwọn korira iṣẹ ọkunrin, nwọn si korira işẹ ibi, nwọn si korira işẹ eşu ninu Imọlẹ ni wọn, ẹni Ọlọrun ni wọn, nwọn ni suuru, Ori wọn si fapo ero wọn si pe Olododo ni wọn nitotọ. nkan le kọkọ le fun wọn, şugbọn igbẹhin aiye wọn yio si dun ju oyin lọ.

Nitori Ọlọruun ti ki i si lẹhin alabosi, Ọlọrun ti ki si lehin "Baba ngbimọ" nibẹ pẹlu awọn awọiyewagere na. Eso wọn yio si dara pupọ, Oluwa rere, a fi titobi ati ọla rẹ bẹ ẹ, gba wa lọwọ atunida ati opurọ kẹnimani o.

Akiyesi

Ẹnikẹni ti o ba fẹ ra Iwe "IROHIN IMỌLẸ" ni ILỌRIN ati agbegbe rẹ yio ri ra lọdọ Asoju wa, Oloye Titus B. I gun
India Insurance Co. Minista Quarter, ILỌRIN
Kọbọ meji (2D) pere ni nta a.

*OLOTU*

# Yẹ Irawọ Rẹ wo

AQUARIUS (Jan 20.- Feb 18) Işẹ rẹ nfẹ ọpọ suru, nitoripe gbogbo nkan ko le ma lọ deede gẹgẹbi o ti fẹ awọn ẹlẹgbẹ rẹ yio şe idilọwọ fun ọ pupọ, o tọ ki o huwa re si awọn ẹlẹgbẹ rẹ

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Ohun ti o nro lọkan dara jọjọ, şugbọn ibaşepọ iwọ pẹlu ẹnikan ko ni şe deede ki o lọ şe abẹwo awọn ọrẹ rẹ yio şe ọ ni ọpọlọpọ ire

ARIES (Mar 21 - April 19) Iwọ yio şe orire diẹ loni, Maşe ja bẹni ki o maşe wahala, fun ifasẹhin tabi afojudi ti nwọn ba şe si ọ. Iwọ yio şe gbọnmisi omi ko to pẹlu olufẹ rẹ.

TAURUS (April 20 - May 20) Lo agbata ore ti o mbẹ fun ọ loni lati fi pari edekoyede kan ti o wa larin irẹ ati ẹnikan. Maşe gbagbe ileri ti o şe ki o si lọ mu şẹ. Okunrin kan nfẹ ire fun ọ.

GEMINI (May 21 - June 20) Iwọ yio ti lpa işẹ şl şe pupọ şe arẹ. Nipa itẹlọruu ni eyi fi le ri bẹ tọju alafia ara rẹ kio si rin irin faaji lọ si ode tabi ki o kuku joko nile.

CANCER (June 21 - July 20) Anfani yio wa ninu işẹ rẹ de ipo ti gbogbo enia yio ma gbadun rẹ, O yẹ ki o ba wọn lọ si apejẹ kan loni iwọ yio şe orire gọbọyi nibẹ.

LEO (July 21-Aug 22) Bi o ba le şe suru, ki o si lo ọgbon ori rẹ, iwọ yio jere nibi işẹ rẹpẹtẹ.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Ayafi bi o ba le gba isimi, ki o sun bi bẹkọ, iso ni iwọ yio ma so gburu pa olufẹ rẹ obinrin nwọn o ranşẹ wa pe ọ si bi kan, oni dara fun irin ajo lọ silu okere.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Otutu yio fẹ mu ọ lori ore kan ti o ti şe şugbọn bi o ba fi ọrọ na silẹ bẹ ire ni yio gbẹhin rẹ ọjọ oni dara fun ọ lati ba obinrin şire pọ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ọjọ oni dara lati lọ ke si awọn ọrẹ rẹ ati fun işẹ ifẹ yio si gbilẹ larin iwọ ati olufẹ rẹ, akoko na niyi lati pari ede koyede ti o wa larin iwọ pẹlu enia.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Joko jẹjẹ masi se da rudurudu silẹ Iwọ yio si jẹun ayọ, iwọ yio jẹ igbadun pẹlu obinrin ti o fẹ

CAPRICORN (Dec 22-Jan 19) Ire yio ba ọ jọ loni, iwọ yio si ba obinrin kan şere ako ti ara rẹ yio gbẹkan maşe aşeju ki o ma ba di ija.


AWỌN EGBOGI ATAMATASE PATAKI TI O WA LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU ARUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU EKINI:-

**SEDO – PAYAL**



(IPARA BI ORI)

Jẹ ojulowo egbogi lati fi şe tosan orisirisi arun awọn ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara gẹbi ọwọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi didun nigbakugba narun tabi akọ Inarun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela lapa ẹpa Ara sisu Alefọ Ekusa lori ọmọde tabi agbalagba egbo ẹsẹ tabi Adaajina egbo ẹsẹ ati orisirisi awọn amodi tabi awọn arun ara omiran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI

**Furunculosin**

Dara pupọ julọ fun awọn ti amodi ti a darukọ wọn si oke iwe yi ba nyọ lẹnu nitoripe işẹ rẹ ni lati m mu gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" enia, san patapata a si ma a şe ribiribi ninu "oju" enia pẹlu. Awọn ti oju wọn a nia "nsu" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o bdai enipe nkankan wa afara si oju wọn yio bẹrẹ si riran Kedere.

Bi o ba ti le gbiyanju lati ma lo egbogi Jamani yi dede fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbọnşẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbọnşẹ dede lojojumọ tabi ti igbọnşẹ wọn ma nle korokoro nipa bayi jẹdijẹdi a bẹrẹ si ma yọ wọn lẹnu bẹni o si dara fun lilo fun awọn onijẹdijẹdi pẹlu awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn rọbirọbi ti wọn nta kakiri Şọbu ilu Eko ati igberikọ Bere wọn ni Şọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin o

Ẹ ku owurọ o, ẹnyin onkawe irohin Imọlẹ, gbogbe yin ni mo ki patapata nko ni olodi kan, Mo ki Olotu na pe, ẹ nlẹ mbẹun o, mo tun ṣi fila fun awọn oṣiṣẹ irohin Imọlẹ na, ẹ ko ni ṣe ti ni ile aiye yin ati emi na pẹlu,

Ilu Ẹpẹ ni mo wa, ti mo fi ri iwe Irohin Imọlẹ ka pe Woli Agbona ti ṣọọṣi rẹ wa ni Idi Oro tun gba ẹiyẹ ajẹ laiya Obinrin kan laipe yi, Eyi mu mi ranti awọn Atinga lọjọ kini ti nwọn bẹresi fi ọna aiye-deru dẹruba awọn olododo agbalagba Obinrin ti ko ni ajẹ pe awọn ni ajẹ, Okiki wọn kan to bẹ gẹ nigbana ti o fi jẹ wipe awọn omugọ ẹda ngn u iya wọn lọ pe Ki awọn atinga ba wọn yẹ iya wọn wo boya o ni ẹyẹ tabi ko ni,

Ira ti nwọn ba sọ pe ko ni ajẹ oyege, eyiti nwọn ba sọ pe eni ajẹ di pe ki nwọn yẹju rẹ lara

Awọn Atinga wọnyi ko ni ohun meji ti nwọn alo ju "abamoda" lọ,

Mo ṣe iranti ọjọ buburu eṣu gbomiwẹ kan ni Abẹokuta nigbati awọn Atinga wọle tọ iya Alhaji kan ti nwọn si mu ni ajẹ laseko ti ọmọ rẹ ko si ni ile,

Nwọn ṣe ẹtọ inu wọn fun Iya na, ṣugbọn nigbati ọmọ rẹ de, o fi gbigbọ ṣe alaigbọ, o rọra wọle tọ awọn alatinga na nibiti nwọn gbe de si, o si kunlẹ ki wọn pe wọn ṣeun nipa iya on ti wọn mu ni ajẹ, ti nwọn si ba on yọ ẹiyẹ ajẹ na kuro lara rẹ,

Ẹnyin onkawe mi njẹ ẹ mọ ohun ti Alhaji na ṣe? Ko ṣe ẹni ko ṣe eji, nṣe ni o ti kọboko bọ wọn lara, oju ferese ni awọn atinga na gba salọ ti nwọn ko fi gbọro wọn ni ilẹ Ẹgba mọ lailai, Iyẹn bẹ ẹ. Ọlọrun kan,

Mo ni ọrọ pupọ ti ngo bere lọwọ Woli Agbona laipẹ ojo mo si fẹ ki oda mi lohun ni ẹkunrẹrẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ maa reti mi Woli Agbọna

ENGMỌ de, ewo nitl ara bibo? Ki enia dudu di enia pupa. Ngo ma sọ ohun ti mo wi wẹrẹ yi ni ọjọ rere, ka pade ni ayọ

KIYESI

"Ẹla ni ọrọ" o, toto oṣebi owe nko fi ọrọ ti Woli Agbara we ti awọn Atinga o? Toripe aiye ṣoro o.

## Asọ Ọlọpa Fun Ẹgbẹ Oselu Bi?

Ni ọjọBọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun osu yi ni awọn ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) nse ikilọ fun ẹgbẹ Dẹmọ NNDP ti nse akoso ijọba Ipinlẹ Iwọ orun Naijiria pe ki nwọn ṣiwọ ninu iwa janduku ikorira ati ijiya ti awọn ẹgbẹ na nfun awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ati Afẹnifẹre to wa ni Ipinlẹ na ni kiakia ati pe awọn fun awọn ọmọ ẹgbẹ Dẹmọ ni ọjọ meje lati fi iwa na silẹ.

Dokita Kingslay Mbadi we igbakeji olori ẹgbẹ Alakukọ ati minista alakoso eto ẹkọ ofurufo si sọ eyi ninu ipade kan to ba awọn oniwe irohin ṣe ni ile iṣẹ rẹ ni ọjọ ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹrindinlogun osu yi ati pe ti nwọn ko ba tete fi iwa na silẹ awọn yio gbẹsan iwa na ni kiakia

Oloye Akinfosile to jẹ minista alakoso eto waya ati ifi iwe ransẹ si ilu okere ati alaga ẹgbẹ Alakukọ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si wa ninu ipade na, oloye Akinfosile si sọ ninu ọrọ rẹ pe awọn ijọba ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria si tun gbero lati fun awọn ẹgbẹ oselu an ni asọ ọlọpa lati ma wọ

Ninu afikun ọrọ Oloye Akinfosilẹl o sọ pe awọn Ijọba ipinlẹ Iwọ Orun ngbimọ eyi ati lati pin Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria si agbegbe Idibo Ijọba apapọ ati lati mura silẹ fun eto idibo fun ile Igbimọ ṣofin apapọ Ijọba Naijiria.

Oloye Kọlawọle Balogun to tun wa ninu ipade na tun sọ pe awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun tun ngbero lati ṣe aiyedaru idibo si Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ Orun

Agbọrọsọ fun Ijọba Ibinlẹ Iwọ Orun Naijiria fi ye onirohin wa pe gbogbo ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ sọ pe irọ ni gbogbo rẹ patapata ati pe Ijọba Ipinlẹ na ko si gbero nkankan to jẹ mọ gbogbo ọrọ ti awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ

# Awon Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu ṣiṣe iwosan ati egbo-ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ko ni yọọ lẹnu m oso ati ajẹ to ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohuni oba si dawọle rẹle ni yio ja si awọn baba. Iiawo ti o Sbo""o gba asọ lọ wọ enia ko ni riọ mọ ye owo 20/-

Iwe egbogiajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wwọnu iae yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọka ṣaṣa w arun ti o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arunrun tabiniasasi kan le pa ọ mọ. Iye owo 25/-

Turari Ẹyọnu Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ṣalaye rẹ Ajẹ ati abatenijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwe ko ni mọ atta ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo yio si wa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/- |
| Itumọ JosẹfuAlala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| Lilo ati agbara Psalm Iṣẹgun l o r i awọn Ajẹ pẹlu Turari | 30/- |

## APEJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni Ile itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ransẹ fun ọja ẹ. Adirẹsi mi niyi:—

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni garaji Iddo, Mushin, Ikorodu road ati gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ri i ra wa si ọdọ mi ngo ta fun.

**J. O. Shoyinka**
c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their;*—
MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:*—
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street**
Phone21985, Lagos.

# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

NO, 732 TUESDAY JUNE 30, 1964 (2D)


## Alhaji Masha Fe Lo Si Ilu Oyinbo

EKO: Ni dede agogo mejo ae ana ni irohin de ile ise wa pe Alaga Ijoba Eko Alhaji A. F. Masha fi Eko sile ni ojo Aje ti ise ojo kokandilogun osu yi lo si Londonu gege bi akoko irin ajo re si ilu Lausanne ni Switzerland lati lo fun eto ipade kan eyiti awon orile ede agbaiye yio se lori akoso Ijoba ibile

Ipade na yio bere ni ilu Switzerland ni ojo Aje ti ise ojo kefa osu keje Odun yi Alhaji A.F Masa yio ko se abewo se abewo si ilu Londonu fun igba die ki o to lo si ilu Switzerland lati lo se amo ju to igbimo Ijoba ilu Eko ninu eyiti gbogbo awon ijoba ibile gbobgo agbaye yio wa lati se asoju ijoba ibile ilu won

Gegebi irohin lati ile ise ijoba ibile E o nwon fi ye oniwe irohin pe alaga Ijoba ibile na yio de si ilu Eko lehin ti nwon ba pari ipade na ni ojo Eti eyiti ise ojo k ma osu keje Odun yi

Awa oniwe irohin I olo ki Alhaji Masha pe, won ku ipa emo o, alo ada ra abo a si sunwon.

## Oba Alaiyeluwa Akarigbo So Pe:

# KO SI ROGBODIYAN NI IJEBU — REMO

SHAGAMU:— Oba Moses Sowemimo Awolesi Akarigbo ti Ijebu Remo ati Olori ile Igbimo lobaloba Ipinlo Iwo Orun so oro re fun onirohin wa pe iro ni awon Igbimo afunnisho ilu Remo pa'pe ko si alafia ni ilu on.

Oba na so ninu oro re pe ki o to, to igbati awon Igbimo afunnisho ti Ijebu Remo ti gbero lati da owo-osu on duro ni on ti pe gbogbo awon omo egbe oselu egbe Afenifere, egbe Ala kuko ati egbe Demo to wa ni agbegbe Ijebu Remo lati se ipade nipa iwa janduku ati iwa ehanna ti awon omo egbe oselu na nhu ni agbegbe na ati lati le je ki eto ofin rere wa ni agbegbe na.



Oba Awolesi
Akarigbo I jebu RemO

Ninu oro ti Oba na ba oniwe iro in wa so lose to koja ni Aafin re ni Oba na tun fi ye onirohin wa pe awon olori egbe Alakuko, egbe Olope ati egbe Demo lo si fun on ni idanilo ju pe ko ni si iwa janduku ati iwa ehanna mo ni agbegbe Ijebu Remo mo.

Oba Akarigbo tun fi ye onirohin wa pe on tun fi esun na si iwaju Gomina Ipinle Iwo Orun Olola Odeleye Fadan nsi lasiko irin ajo ibewo si agbegbe Remo nipa eto ofin rere ti awon janduku egbe oselu kan fe je ki o Iri ni agbegbe na.

### IFILO

Oba Awolesi tun so pe on tun fi oro na lo awon Ijoye to wa ni agbegbe on lati ba awon enia won soro nipa iwa jegidijı gan to nbe sile ni agbegbe won.

Siwaju sii Oba Awoles tun so pe lati igbati igbimo afunnisho yi ti fi esun na kan on ati lati da owo osu on duro ni awon ijoye on ti nse ipade lojojumo ni Aafin on lati le mo gegebi nwon yo ti se nipa iru iwa ti awon igbimo na nhu.

Oba Awolesi si tun so on ko ni oro kankan lati so fun awon onirohin nipa iwa ti awon igbimo afunnisho na nhu pelu on ati pe o si je ohun to ya on lenu lati ri iru iwa ti awon enia kan to je pe nwon kan ko won jo si ile igbimo na lati ma a gba iru ero be pelu on.

Oba na so pe on ti mura sile lati so ti enu on fun won nigbakugba ti ijoba ipinle Iwo-Orun ba pe on lati so ti enu on nipa esun ti awon igbimo afunnisho na fi kan on.

Nipa ipari oro re Oba Awoles fi ye oniwe irohin wa pe igbakugba ti nwon ba pe on lati Ibadan lati wa so ti enu on pe on yio so Alakoso to amojuto eto Ijoba ibile ati pe ti on ba ti so ti e u on fun wontan, on yio fi eda iwe oro ti on so na ran se si ile ise iwe iroh n

Irohin tun fi ye wa lati owo oniwe irohin ni Ibadan ni owuro ojo Aje ti se ojo kokandinlogbon osu kefa odun yi pe Olotn ipinle Iwo Orun Oloye Akintola ro awo oba meta t awon igbimo afunisho so pe nwon yio da owo won duro ati pe osi kesi awon Oba n. lati ni isowopo jarin ara won

Oloye Akintola t u n ro awon igbimo afunnisho na lati n i iter ba fun awon oba f u n wonyi nitoripe baba ni awon Oba n a je fun awon enia Ipinle Iwo Orun. Ninn awon Oba ti awon Igbimo afunnisho ge owo-osu won di kobo kan soso lodun n i awon Oba meji k a n ni ekun Ekiti ati Oba Akarigbo ilu Remo eyiti awon igbimo afunnisho ti Ijoba Remo ge owo r e ku si kobo kan soso lodun ninu ose to koja.

## Dokita Allen Mu Ori bo!

LATI OJU EWE KINI

Ogbeni M. A. Odesanya agbejoro fun Ogbeni V. L. Allen.

Adajo wa s o fun Ogbeni Victor Lneonard Allen pe, on gba iduro re ati pe on yio fun ni a w o n nkan meta ti o ni lati muse

Ekini ki iwe irinna ajo (Passport) re wa ni odo akowe agba ile ejo nla.

Ekeji ki o fi igba pounn se iduro ati eketa ko gbodo rin ju igba ibuso lo si ilu Eko.

Esun ti won ka si lorun ni wipe o nko egbe kan jo eyiti olodi si ofin iselu Naijiria eyiti ofe fi doju Apapo Ijoba dele, ni ojo ketadinlogun osu ke f a odun yi ni o g b e n i V. L. Allen fi ara han niwaju adajo kekere kan ni Eko.

Nigbati oro ejo re na tun wa sile ejo na ojo Eti tise ojo kerindinlogbon osu kefa ninu odun yi, ni agbejoro Ijoba ogbeni M O. Onafaloju so pe on ko ti ye ejo na wo daada nitoripe ni owuro ojo na ni on to mo nipa ejo na.

A fi igbati odi ojo kokandinlogb o n osu kefa ni adajo agba gba iduro re


Printed and P blished by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21935
Editor:- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street Lagos 30/6/64